

# Pípèsè Owó fún Okòwò Kékeré rẹ

2022-2023

**New York Immigration Coalition**
nyic.org

# TÁBÌLÌ ÀKÓÓNÚ

## I. ÌFIHÀN ÌBẸ̀RẸ̀PẸ̀PẸ̀


Bí A Ṣe Ńlo Ìtọ́sọ́nà Yìí 1


## II. AGBÁRA OKÒWÒ RẸ LÁTI YÁ ÒWÒ


Níní Òye Agbára Okòwò Rẹ Láti Yá Owó 2

Fífẹsẹ̀ Agbára Okòwò Rẹ Láti Yá Owó Múlẹ̀ 3


## III. ÀWỌN ÀṢÀYÀN ÌPÈSÈ OWÓ FÚN OKÒWÒ


Mímú Owó Jáde Lápò Ara Ẹni 4

*Àwọn Ọ̀rẹ́ & Ẹbí* 5

*Pípèsè Owó nípasẹ̀ Èèrò* 6

*Àwọn Ààyè Ìbáraẹnijíròrò fún Pípèsè-Owó-nípasẹ̀-Èèrò* 7

Àwọn owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ 8

Owó yíyá 9

*Àwọn Ìgbésẹ̀ láti Bèèrè fún Ẹ̀yáwó* 10

*Ìfìwébèèrè Ẹ̀yáwó fún Okòwò Kékeré Gbogbogbò Ìṣàyẹ̀wò Àkójọ* 11


## IV. ÀWỌN OHUN ÀMÚLÒ


Àwùjọ Ènìyàn Ìpínlẹ̀ New York 12

Àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìpèsè-owó Ìdàgbàsókè

## Bí a Ṣe Ńlo Ìtọ́sọ́nà yìí

Ohun kan tó ṣe pàtàkì púpọ̀ nípa ifilọ́lẹ̀ tàbí ìmúgbèrú okòwò kékeré ni níní òye àwọn àṣàyàn tó wà nílẹ̀ láti rannilọ́wọ́ láti bá àwọn àìní okòwò rẹ pàdé. Àwọn okòwò kékèké tó jẹ́ ti àwọn àṣíwá-sí-ìlú láti ibòmíràn jẹ́ bíi 33.8% lára àwọn tó ní okòwò àdáni tó ń gbé ní Ìpínlẹ̀ New York, èròǹgbà wa sì ni láti mú àwọn àlàyé àti àwọn ohun àmúlò pàtàkì tí a yàsọ́tọ̀ wá fún àwùjọ ènìyàn yìí, láti lè ran àwọn àṣíwá-sí-ìlú láti ibòmíràn tó ni okòwò kékèké lọ́wọ́.

Ìwé ìtọ́sọ́nà yìí yóò jẹ́ irin-iṣẹ́ tí àwọn àṣíwá-sí-ìlú láti ibòmíràn tó ni okòwò kékèké lè lò gẹ́gẹ́ bí ìfihàn ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ sí fífẹsẹ̀ agbára okòwò láti yáwó múlẹ̀, gẹ́gẹ́ bí àwòpapọ̀ àwọn àṣàyàn tó wà nílẹ̀ fún ìpèsè owó fún okòwò, àti gẹ́gẹ́ bí àlàkalẹ̀ lápapọ̀ fún ìfiwébèèrè fún ẹ̀yáwó. Àṣàyàn ìpèsè owó fún okòwò yòówù tí o bá yàn yóò ní ipa lórí àgbékalẹ̀ okòwò rẹ àti ọjọ́-iwájú ìpèsè owó fún okòwò rẹ. Ó ṣe pàtàkì láti ronú nípa bí ìpèsè owó ṣe lè ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dé àwọn ibi-àfẹ́ẹ̀dé okòwò rẹ àti bí ó ṣe lè wúlò fún àwọn àìní rẹ tó jẹ mọ́ owó.

Ìtọ́sọ́nà yìí kò sọ nípa àwọn ohun mìíràn tí o nílò bíi ìwé-àṣẹ tàbí ìgbaniláàyè. A gbọ́dọ̀ lo ìtọ́sọ́nà yìí bíi àlàyé lápapọ̀ fún àwọn èrò tó jẹ mọ́ ìpèsè owó fún okòwò. Jọ̀wọ́ ṣàyẹ̀wò Ìtọ́sọ́nà Okòwò Kékèké fún Aṣíwá-láti ìlú ibòmíràn ní **https://www.nyic.org/immigrant-small-business-guide/** fún àwọn ohun àmúlò síwájú síi.

## Nílí Òye Agbára Okòwò Láti Yá Owó

Kí o tó ṣe ìpinnu nípa ìpèsè owó fún okòwò rẹ, ó yẹ kí o fìdí agbára okòwò rẹ láti yáwó múlẹ̀. Agbára okòwò **láti yáwó**, gẹ́gẹ́ bí agbára ènìyàn kan láti yáwó, a máa mú kí àwọn ayánilówó lè mọ̀ bóyá wọ́n lè yá ọ lówó láìséwu. A máa ran àwọn ayánilówó lọ́wọ́ láti ṣègbéléwọ̀n ṣíṣeéyálówó rẹ, tàbí bí okòwò kan ṣe kún ojú òṣùwọ̀n tó láti fún ní àtìlẹ́yìn ìpèsè owó. Àwọn ayánilówó a máa mọ èyí nípa wíwo ìtàn owó níná rẹ àti agbára rẹ láti san gbèsè padà.

Orúkọ okòwò ẹni ni a fi ń ṣí àkọ́ọ́lẹ̀ agbára okòwò láti yáwó. Èyí a máa jẹ́ kí ó dánilójú pé ọ̀rọ̀ owó okòwò ẹni àti ọ̀rọ̀ owó ara ẹni kò papọ̀. Èyí ṣe pàtàkì nítorí pé:

- Ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ fún àwọn ọ̀rọ̀ owó méjèèjì a máa pa ọ̀rọ̀ owó ti ara rẹ mọ́ kúrò lọ́wọ́ àjálù yòówù tó lè kojú okòwò rẹ
- Okòwò rẹ lè bẹ̀rẹ̀ láti máa kọ ìtàn ọ̀rọ̀ owó, èyítí yóò mú kí ṣíṣeéṣe rẹ láti yáwó àti láti wá ọ̀nà ìpèsè owó mìíràn rọrùn síi
- Yóò rọrùn fún ọ síwájú síi láti dá àwọn ìnáwó tó jẹ mọ́ okòwò rẹ mọ̀ yàtọ̀ fún èrèdí sísan owó-ìlú

## Ìtàn Ẹ̀yáwó

Ìtàn ẹ̀yáwó a máa ní ipa lórí àwọn àǹfàní tó wà fún ìpèsè owó fún okòwò, iye owó fún sísan sí ilé-iṣẹ́ ìbánidófò, èyí sì tún máa ń ran àwọn aláàbáṣiṣẹ́pọ̀ okòwò àfojúsọ́nàfún, àwọn apèsè ọjà, àti àwọn aláàtúnta ọjà lọ́wọ́ láti lè ṣe ìpinnu bóyá wọn yóò fẹ́ láti ṣiṣẹ́pọ̀ pẹ̀lú okòwò rẹ. Ìtàn ẹ̀yáwó tún máa ń jẹ́ kí àwọn aláàbáṣiṣẹ́pọ̀ àti àwọn ayánilówó mọ̀ bóyá okòwò rẹ lè dàgbàsókè, kó sì ní èrè lórí.

Àwọn ayánilówó tún máa ń lo ìtàn ẹ̀yáwó láti mọ̀ bóyá kí wọ́n fọwọ́sí yíyá okòwò kan lówó. Àwọn ìtàn ọ̀rọ̀ owó ara ẹni àti ti okòwò ẹni ni a máa ń gbéyẹ̀wò nígbàtí a bá ń ṣe ìpinnu nípa kíkún ojú òṣùwọ̀n fún ẹ̀yáwó.

Nígbàtí àwọn ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe ìjábọ̀ nípa ìtàn ẹ̀yáwó ẹni, bíi Experian, Equifax, àti Dun & Bradstreet bá ṣe àyẹ̀wò ìtàn ẹ̀yáwó rẹ, wọ́n máa ń lo àwọn **ohun** pàtàkì wọ̀nyí:

| | | |
|---|---|---|
| Iye Ọdún tí o ti ń ṣe Okòwò | Iye ẹ̀yáwó tí o bèèrè fún laarin oṣù 9 tó kọjá kẹ́yìn | Iye ẹ̀yáwó tí o bẹ̀rẹ̀ laarin oṣù 6 tó kọjá kẹ́yìn |
| Iye àsanpadà tí o kò san wọlé lásìkò | Títóbi Ilé-iṣẹ́ àti Okòwò ẹni | Ìtàn àsanpadà fún oṣù 12 tó kọjá |

| Bí a ṣe Ń Fẹsẹ̀ Agbára Okòwò fún Ẹ̀yáwó múlẹ̀ | |
|---|---|
| **Yan Ìlànà Okòwò kan** | • Gbogbo ìlànà okòwò a máa ya okòwò rẹ sọ́tọ̀ yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ owó ti ara rẹ àfi bí ó bá jẹ́ okòwò àdànìkanni<br>• O lè kọ́ ẹ̀kọ́ síi nípa ìṣàgbékalẹ̀ okòwò níbí: https://www.nyic.org/immigrant-small-business-guide/ |
| **Gba Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Agbanisíṣẹ́ (EIN)** | • EIN tí a tún mọ̀ sí Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Owó-ìlú Ìjọba Àpapọ̀. A máa ń lòó láti fi dá okòwò mọ̀. Okòwò rẹ nílò EIN kí o lè máa san owó-ìlú, kí o lè ṣí àkáùntù ilé-ìfowópamọ́ fún okòwò, a`ti kí o lè kọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó, ìgbaniláàyè, àti ìwé-àṣẹ<br>• O lè kọ̀wé bèèrè fún EIN nípa lílo irin-iṣẹ́ IRS yìí: https://www.irs.gov/ein |
| **Ṣí Àkáùntù Ilé-ìfowópamọ́ Fún Okòwò** | Ṣíṣí àkáùntù ilé-ìfowópamọ́ fún okòwò ẹni ṣe pàtàkì láti lè ya àwọn ìnáwó ara ẹni rẹ sọ́tọ̀ kúrò lára ìnáwó okòwò rẹ. Àwọn ilé-ìfowpamọ́ náà lè dúró bíi olùdúró lásìkò tí ènìyàn bá fẹ́ yá owó |
| **Fẹsẹ̀ Ìtàn Ọ̀rọ̀ Owó Múlẹ̀ Pẹ̀lú Àwọn Olùtajà/Olùpèsè Ọjà** | Ríra ọjà, àwọn ohun èlò, àti àwọn nǹkan mìíràn látọwọ́ àwọn olùtajà àti olùpèsè ọjà a máa rannilọ́wọ́ láti kọ ìtàn ọ̀rọ̀ owó. |


## Mímú owó jáde lápò ara ẹni

**Mímú owó jáde lápò ara ẹni**, tàbí Títánṣòroaraẹni-fúnraaraẹni, jẹ́ pé o fi owó ara rẹ ṣe okòwò. Kìí ṣe ohun tó wọ́pọ̀ fún àwọn olùdókòwò tuntun láti ní àwọn ohun àmúlò owó láti lè pèsè owó ti okòwò wọn nílò, nítorí náà wọ́n gbọ́dọ̀ ronú nípa àwọn ohun mìíràn bíi ìpín nínú èrè ilé-iṣẹ́ kan tàbí ìbánidókòwò, káàdì kírẹ́díìtì ara ẹni, tàbí ẹ̀yáwó.

Mímú owó jáde lápò ara ẹni a máa gba àwọn olùdókòwò láàyè láti ní òmìnira láti ṣe ìpinnu àti láti gba ìwọ̀n 100% èrè tó wọlé lórí ìtajà àti ìbánidókòwò. Ó ṣe pàtakì láti rántí pé pẹ̀lú mímú owó jáde láti àpò ara ẹni, olùdókòwò nìkan ni ó ni gbogbo ewu àti ojúṣe tó níí ṣe pẹ̀lú okòwò náà.

Nígbàtí o bá ń mú owó nínú àpò ara rẹ, ìwọ á fẹ́ kí okòwò rẹ ní èrè lórí lásìkò. Ìwo yóò fẹ́ láti tún lè fi owó mìíràn kún èyítí o kọ́kọ́ ná sórí okòwò rẹ.

Dípò kí o kọ ẹnu sí àwọn adánilókòwò tàbí ilé-ìfowópamọ́, Àwọn Atánṣòroaraẹni-fúnraaraẹni a máa bèèrè àtìlẹ́yìn lọ́wọ́ àwọn ẹbí àti ọ̀rẹ́ wọn tàbí kí wọ́n lọ fún pípèsè-owó-nípasẹ̀-èèrò.



## Àwọn Ọ̀rẹ́ àti Ẹbí

Àwọn ọ̀rẹ́ àti ẹbí ní ó máa ń sábà jẹ́ orísun àtìlẹ́yìn àkọ́kọ́ fún àwọn tó ní okòwò kékèké nítorí àsopọ̀ tí wọ́n ní pẹ̀lú rẹ àti nítorí ìgbàgbọ́ wọn nínú ibi-àfẹ́dé àti agbára rẹ.

Nítorí àwọn ìdènà kan tí àwọn okòwò kan máa ń kojú nígbàtí wọ́n bá ń kọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó àti tí wọ́n bá ń wá àwọn adánilókòwò, àtìlẹ́yìn owó láti ọ̀dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ àti ẹbí máa ń jẹ́ ohun àmúlò tó ṣe kókó. Wọ́n lè ṣe àtìlẹ́yìn fún okòwò rẹ nípasẹ̀ àwọn ẹ̀bùn, ẹ̀yáwó, tàbí ìbánidókòwò. Wọ́n sì tún lè pèsè owó láìní èrò láti gba ohunkóhun padà tàbí kí wọ́n pèse ẹ̀yáwó tó ní ètò àsanpadà tí yóò rọrùn fún ọ.

Máa sọ òtítọ́ nígbà gbogbo nípa àwọn ewu àti ojúṣe tó wà nínú okòwò rẹ, kí o sì fààyèsílẹ̀ fún òye tó hàn kedere nígbàtí o bá ń yá owó. Ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì wọ̀nyí nígbàtí o bá ń wá àtìlẹ́yìn láti ọ̀dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ àti ẹbí:

| | |
|---|---|
| **Sọ àsọyé ohun gbogbo ní pàtó** | • Bèèrè fún iye owó kan pàtó fún ibi-àfẹ́dé kan pàtó |
| **Máṣe farapamọ́** | • Inú àwọn ìbánidókòwò wo ni o fi owó rẹ sí?<br>• Kíni àwọn ohun tó jẹ́ ojúṣe rẹ?<br>• Kíni àwọn ewu tó wà nínú rẹ̀? |
| **Ní Àwọn Àjọhùn tí a Ṣàkọsílẹ̀ èyí tó Ṣàlàyé Àwọn Ìfohùnṣọ̀kan nípa Ẹ̀yáwó** | • Iye owó tí o fẹ́ yá pẹ̀lú ìwọ̀n àsanlé orí rẹ̀<br>• Èrèdí ẹ̀yáwó<br>• Àjọhùn nípa àsanpadà- sísan àpapọ̀ owó náà lẹ́ẹ̀kanṣoṣo tàbí sísan-án láti ìgbà dé ìgba; iye tí o gbọ́dọ̀ san nígbà àsanpadà kọ̀ọ̀kan<br>• Àkókò Àsanpadà tó ṣàlàyé ìgbà tí àsanpadà yóò bẹ̀rẹ̀, tó sì sọ àsọyé ní pàtó àkókò tí o gbọ́dọ̀ sanwó náà tán<br>• Àwọn àtúnbọ̀tán àìsanwópadà |

## Pípèsè-Owó-nípasẹ̀-Èèrò

Pípèsè-Owó-nípasẹ̀-Èèrò ni bí o bá ṣàkójọ owó fún àwọn iṣẹ́ àti ìnáwó tó jẹ mọ́ okòwò rẹ látọwọ́ àwọn ènìyàn láwùjọ. A máa ń sábà ṣe èyí nípasẹ̀ àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò lórí ayélujára.

Oríṣi pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò méjì pàtàkì ni ó wà tí o lè lò fún okòwò kékeré rẹ:

- Ìpèsè Owó Tó Dá Lórí Ìṣètọọrẹ - wíwá owó lọ́wọ́ àwọn ènìyàn láti ṣàtìlẹ́yìn fún okòwò rẹ láì gba ohunkóhun padà lọ́wọ́ rẹ. Ìlànà tì kò ní ewu tó ga yìí, tó sì ní èrè púpọ̀ nínú jẹ́ èyí tó dára gidi fún àwọn okòwò kékèké
- Ìpèsè Owó Tó Dá Lórí Ẹ̀bùn - àwọn tó dáwó yóò gba áwọn ẹ̀bùn kékeré, àwọn ọjà, tàbí àwọn ìpèsè iṣẹ́ ní pàṣípààrọ̀ fún dídáwó wọn. Bí àpẹẹrẹ, bí o bá nílò láti ṣàkójọ owó fún àdìrò tuntun fún ilé-iṣẹ́ rẹ tí o ti ń ṣe búrẹ́dì àti àwọn nǹkan bẹ́ẹ̀ mìíràn, olè fún wọn ní tíkẹ́ẹ̀tì ẹ̀dínwó fún àkàrà òyìnbó (kéèkì) kékèké kọ̀ọ̀kan lọ́fẹ̀ẹ́ bí wọ́n bá ti dáwó

## Àwọn Àǹfàní àti Àlébù Pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò

Àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò fún pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò a máa pèsè ọ̀pọ̀ àwọn àǹfàní bíi mímú ọjà olórúkọ kan gbajúmọ̀ síi, ríranniIọ́wọ́ láti ní ọ̀pọ̀ oníbàárà, àti dídín ewu ọ̀rọ̀ owó tó lè wáyé kù. O tún lè wá àwọn ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe irú ìpolongo pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò kan náà láti lè mọ irú ẹ̀bùn ìwúrí tí wọ́n máa ń fúnni, àti bóyá wọ́n ń ṣe àṣeyọrí.

Ṣùgbọ́n ṣá, àṣeyọrí pẹ̀lú pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò lè pín sọ́tọ̀ọ̀tọ̀, èyí sì dá lórí agbára rẹ láti lè kàn sí àwọn ènìyàn tí wọ́n lè ṣètọọrẹ.

Àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò bíi Kickstarter, Indiegogo, àti GoFundMe jẹ́ irin-iṣẹ́ tó dára púpọ̀ fún pípèsè-owó-nípasẹ-èèrò. O lè ṣàgbésóde àwọn àlàyé nípa ọjà tàbí ìpèsè iṣẹ́ kan, o lè ṣètò ibi-àfẹ́dé ìpèsè owó, o sì lè ṣèpinnu iye àsìkò tí o fẹ́ lò fún ìwọ̀nyí. Ṣùgbọ́n ṣá, àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò kan kìí fúnni ní owó náà bí a kò bá dé ibi-àfẹ́dé, wọ́n sì máa ń bèèrè fún sísan owó ààyè ìbáraẹnijíròrò àti ti ìdúnàádúra fún àwọn káàdì kírẹ́dìítì àti dẹ́bítì.



# Pípèsè-Owó-nípasẹ̀-Èèrò Àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò

| Àwọn ààyè ìbáraẹnijíròrò | Àǹfàní | Àlébù |
| --- | --- | --- |
| KickStarter<br>[www.kickstarter.com](www.kickstarter.com) | • Ààyè ìbáraẹnijíròrò tó ti gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀bùn, tó máa ń gbani láàyè láti fún àwọn alátìlẹ́yìn ní ẹ̀bùn ìwúrí gẹ́gẹ́ bíi ọjà fún títà tàbí ẹ̀dínwó<br>• Ààyè ìbáraẹnijíròrò fún pípèsè-owó-nípasẹ̀-èèrò tó gbajúmọ̀ jùlọ | • O lè gba owó náa bí o bá dé ibi-àfẹ́dé rẹ nìkan<br>• Owó ààyè ìbáraẹnijíròrò tó jẹ́ ìwọ̀n 5% iye owo náà<br>• Owó sísan fún ìdúnàádúra owó tí a san náà (3%-5%) |
| GoFundMe<br>[www.gofundme.com](www.gofundme.com) | • Ìwọ̀n 0% iye owó náà gẹ́gẹ́ bi owó ààyè ìbáraẹnijíròrò<br>• O lè tọ́jú gbogbo ìtọọrẹ tí o gbà yàlá o dé ibi-àfẹ́dé rẹ tàbí o kò dé ibẹ̀<br>• Àtìlẹ́yìn àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ wà jálẹ ọjọ́ gbogbo | • Àwọn owó sísan fún Ìdúnàádúrà Káàdì Kírẹ́dìítì àti Dẹ́bìítì |
| Indiegogo<br>[www.indiegogo.com](www.indiegogo.com) | • Agbára láti lè yan ibi-àfẹ́dé kan pàtó nípa ìpèsè owó (ibi-àfẹ́dé gbogbo rẹ̀ tàbí ṣíṣófo) tàbí ìpèsè owó tó ṣeé ṣàyípadà (ìwọ yóò gba owó yálà o dé ibi-àfẹ́dé rẹ tàbí o kò dé ibẹ̀)<br>• Indiegogo InDemand a máa jẹ́ kí o lè tẹ̀síwájú láti máa wá ọ̀nà ìkówójọ lẹ́yìn tí ètò ìkówójọ rẹ bá ti dópin | • A máa gba owó kan tó jẹ́ ìwọ̀n 5% iye owó náà gẹ́gẹ́ bi owó ààyè ìbáraẹnijíròrò<br>• Owó sísan fún iṣẹ́-ṣíṣẹ àwọn ẹlòmíràn lórí owó tí o san |

## Àwọn owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀

Owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ jẹ́ ìlànà ìpèsè owó kan fún àwọn okòwò fún ìdí kan pàtó. Ìpèsè owó lè wá látọwọ́ àwọn ilé-iṣẹ́ gbogbogbò bíi àwọn ilé-iṣẹ́ ìjọba, àwọn ẹgbẹ́ alájọṣepọ̀ ilé-ìfowópamọ́/ayánilówó, tàbí àwọn àjọ àìlérènínú.

Nígbàtí o bá ń yá owó, àwọn ayánilówó a máa fẹ́ kí o ṣàfihàn agbára rẹ láti san gbèsè náà padà, ṣùgbọ́n àwọn àjọ tó ń fúnni ní owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ a máa fẹ́ kí okòwò rẹ tẹ̀lé èròǹgbà tàbí ìgbésẹ̀ wọn kan pàtó. Yàtọ̀ sí ẹ̀yáwó, àwọn owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ kò nílò àsanpadà, wọn kìí sì ní ipa lórí àwọn ìpinnu tí a ṣe nípa okòwò ẹni.

Àǹfàní mìíràn tí àwọn owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ tún ní ni pé wọn kìí sábà nílò àyẹ̀wò agbára ẹni láti san gbèsè padà kí ènìyàn tó lè gbàá. Ṣùgbọ́n ṣá, kíkún ojú òṣùwọ̀n fún gbígba àwọn owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ a máa sábà ṣòro púpọ̀, owó-ìlú wà fún sísan lórí rẹ̀, ìlànà sì wà fún bí a ti gbọ́dọ̀ lo owó náà. Nítorí ọ̀pọ̀ lára owó náà tí à ń fífúni dá lórí bí okòwò náà bá ṣe bá èròǹgbà tàbí ìgbésẹ̀ ẹni tó fẹ́ fúnni ní owó náà dọ́gba tó, ìkọ̀wé bèèrè fún owó tí ìjọba tàbí àjọ gbékalẹ̀ a máa ní èèrò tó pọ̀ nìlẹ̀, iye àwọn tó ń ríi gbà sì kéré púpọ̀.



## Owó yíyá

Nígbàtí fífi owó ara rẹ ṣòwò kìí bá ṣe àṣàyàn tí o lè yàn, **ẹ̀yáwó** jẹ́ ohun mìíràn fún yíyàn. Ẹ̀yáwó fún okòwò a máa ràn ọ́ lọ́wọ́ láti mú owó tó ń wọlé-jáde pọ̀ síi, láti ra àwọn ohun àmúlò tí iye owó wọn pọ̀ púpọ̀, àti láti mú okòwò rẹ gbèrú síi.

Yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀yáwó fún okòwò tó wọ́pọ̀, ẹ̀yáwó fún okòwò kékèké a máa wá pẹ̀lú àsanlé tí kò pọ̀ púpọ̀ rárá, pẹ̀lú àsanṣáájú tó ṣeé dúnàádúrá lé lórí, àti ìkọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó tó rọrùn síi.

### Àwọn ohun tí a gọ́dọ̀ ronú nípa nígbàtí a bá ń ṣe ìpinnu láti yá owó:

- Ìṣàmúlò Owó
  - Àwọn ayánilówó máa ń fẹ́ ní òye tó dá gaara nípa bí o ṣe fẹ́ lo owó náà, nítorí náà sọ àsọyé nípa ìdí pàtó tí o fi nílò ẹ̀yàwó náà

- Iye owó fún Sísan
  - Ǹjẹ́ ìwọ yóò lè san iye owó àsanpadà olóṣooṣù ti owó tí ò ń yá náà pẹ̀lú ìrọ̀rùn bí?
  - Ǹjẹ́ ìwọ yóò lè san àwọn owó tó jẹ́ àsanlé nìkan bí?
  - Ǹjẹ́ o lè sún àsanpadà ẹ̀yáwó náà síwájú bí ó bá nílò bẹ́ẹ̀ bí?

- Iye owó
  - Ǹjẹ́ o lè san àwọn owó àsanlé pẹ̀lú ìrọ̀rùn bí?
  - Ǹjẹ́ iye owó kan wà fún sísan bí o bá sanwó náà padà kí àsìkò tí a dá fún ọ tó pé bí?

- Yíyan Àsìkò
  - Àsìkò tó dára jùlọ láti kọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó ní ìgbàtí o kò bá tíì nílò owó náà. Ìlànà ìkọ̀wébèèrè fún ẹ̀yáwó jẹ́ èyí tó ní abala tó pọ̀, nítorí náà, ó ṣe pàtàkì pé kí o mọ̀ àwọn ohun tí o nílò láti ìbẹ̀rẹ̀



<table>
<tr><th colspan="2">Àwọn Ìgbésẹ̀ láti Bèèrè fún Ẹ̀yáwó</th></tr>
<tr><td>Ṣàyẹ̀wò pẹ̀lú àwọn Ayánilówó rẹ</td><td><ul><li>Ní àkọ́kọ́, bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ilé-ìfowópamọ́ agbègbè rẹ tàbí àwọn ẹgbẹ́ ayánilówó tí o ní ìbáṣepọ̀ ìfowópamọ́ pẹ̀lú. Bí ilé-ìfowópamọ́ kò bá sí lára àwọn àṣàyàn rẹ̀, àwọn ẹ̀yáwó látọwọ́ ìjọba ìlú àti ti ípínlẹ̀ àti Àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìpèsè-owó Ìdàgbàsókè Àwùjọ jẹ́ ara àwọn ayánilówó mìíràn tí o lè gbéyẹ̀wò</li></ul></td></tr>
<tr><td>Ṣe ìpinnu nípa iye owó Ẹ̀yáwó tí o fẹ́ Bèèrè fún</td><td><ul><li>Ṣèwádìí iye owó tí o nílò láti ṣe àwọn ohun tó yẹ kí o ṣe</li><li>Ṣèwádìí bóyá iye owó tí o nílò láti san yóò jẹ́ lẹ́ẹ̀kanṣoṣo tàbí láti ìgbà-dé-ìgbà</li></ul></td></tr>
<tr><td>Ronú nípa àwọn ohun tí ayánilówó ń bèèrè fún</td><td><ul><li>Ní òye àwọn ìwé tí ìwọ yóò nílò láti kó lọ pọ̀ mọ́ ìkọwé bèèrè rẹ</li></ul></td></tr>
<tr><td>Ṣe Ìpinnu Ìdí (Bí ìwọ yóò ṣe Lo Owó náà)</td><td><ul><li>Bí àpẹẹrẹ:<ul><li>Ra àwọn ohun èlò tàbí ọjà tuntun</li><li>Rà tàbí kí o ṣe àyálò ilé/ibi-ìtajà kan</li><li>San owó àwọn òṣìṣẹ́</li></ul></li></ul></td></tr>
<tr><td>Ṣe ìṣirò iye owó àsanpadà ẹ̀yàwò rẹ</td><td><ul><li>Ríi dájú pé o lè san iye owó àsanpadà olóṣooṣù náà nírọ̀rùn kí o tó gbà láti yá owó</li><li>Ṣe ìpinnu nípa bí ìwọ yóò ṣe san owó tí o fẹ́ yá náà padà, àti bóyá o fẹ́ iye àsìkò àsanpadà tó gùn tàbí tó kúrú</li><li>Ṣèjẹ́rìí bóyá o lè ṣàyípadà iye owó tí ò ń san lóṣooṣù tàbí bóyá ó jẹ́ iye kan náà nígbà gbogbo</li></ul></td></tr>
</table>

## Ìṣàyẹ̀wò Àkójọ Ìfiwébèèrè Ẹ̀yáwó fún Okòwò Kékeré Gbogbogbò

Lọ́gán tí o bá ti ṣetán láti kọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó, ìwọ yóò nílò láti ṣàkójọ àwọn ìwé *Ọ̀rọ̀* owó àti *Okòwò* fún ìkọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó rẹ.

**Àwọn Àkọsílẹ̀ nípa Ọ̀rọ̀ owó**

Ìwọ yóò nílò àwọn ẹ̀dà tuntun jùlọ ti

- Ìdápadà iye owó-ìlú ara ẹni àti ti okòwò ẹni
- Àwọn àkọsílẹ̀ nípa ọ̀rọ̀ owó, àwọn èyí tó jẹ́
  - Àkọsílẹ̀ nípa èrè àti àdánù, ìwé iye owó tó wà nílé ìfowópamọ́, àti gbólóhùn nípa wíwọlé àti jíjáde owó
- Àwọn àkọsílẹ̀ nípa ara ẹni jẹ́
  - Nọ́mbà ààbò àwùjọ tàbí nọ́mbà ITIN, iye owó tó ń wọlé, ìtàn ẹ̀yáwó, ìtàn ìdúnàádúrà, àti àlàyé nípa àkọ́ọ̀lẹ̀ owó-sísan àti ìkọ̀wégbowó nílé ìfowópamọ́

**Àwọn Ìwé Okòwò**

- Ìlànà àgbékalẹ̀ àti àwọn ìwé mìíràn lábẹ́ òfin
  - Àwọn ìwé tí a fi bèèrè àṣẹ lọ́wọ́ ìjọba láti dá ilé-iṣẹ́ sílẹ̀
  - Ìforúkọsílẹ̀ àti àwọn ìwé-àṣẹ okòwò
  - Àwọn òfin okòwò àti ìlànà ìmúṣẹ́ṣe
  - Ẹ̀dà àjọhùn tí o fi gba ilé bí ó bá jẹ́ pé o yá ààyè lò ni tàbí o yá ohun èlò yóòwù tó ṣe pàtàkì fún okòwò rẹ
- Ètò Okòwò
  - Èyí jẹ́ àǹfàní fún ọ láti sọ fún àwọn ayánilówó pé okòwò rẹ kún ojú òṣùwọ̀n fún ìbánidókòwò náà. Èyí yóò pẹ̀lú àwọn èrò rẹ nípa iye owó tí o nílò, gbólóhùn-ọ̀rọ̀ èròngbà okòwo rẹ, àti ètò ìgbésẹ̀ rẹ.

**Fún àfikún àlàyé nípa àwọn ìwé ọ̀rọ̀ owó àti ti okòwò tí a nílò láti kọ̀wé bèèrè fún ẹ̀yáwó, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí: https://www.sba.gov/funding-programs/loans/7a-loans**

## Àwọn Àjọ Ilé-iṣẹ́ Ìpèsè-owó fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ ti NYS (CDFIs)

Àwọn Àjọ Ilé-iṣẹ́ Ìpèsè-owó fún Ìdàgbàsókè Àwùjọ ń pèsè àtìlẹ́yìn fún àwọn àṣíwá-sí-ìlú láti ibòmíràn, okòwò àwọn obìnrin, àti àwùjọ àwọn ènìyàn tó ń gba owó-ọ̀yà tó kéré nípasẹ̀ ẹ̀yàwó tí àsanlé rẹ̀ kéré, àǹfàní fún ẹ̀bùn owó, àti àwọn iṣẹ́ ìpèsè owó bí àwọn ètò ìkọ́ni olójúkojú àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́.

Àwọn CDFI jẹ́ ohun àmúlò tó dára púpọ̀ láti ráàyèsí ìpèsè owó àti láti ní ìmọ̀ tó wúlò púpọ̀ nípa bíbẹ̀rẹ̀, ìpèsè owó, àti gbígbèrú okòwò kékeré rẹ. Ní ìsàlẹ̀ níbí, ìwọ yóò rí àwọn CDFI tó wà ní NYS tó lè ṣàtìlẹ́yìn fún ọ nínú ìrìn-àjò okòwò rẹ:

| | |
|---|---|
| **Accompany Capital**<br>Accompanycapital.org | **BOC Capital**<br>Boccapital.org |
| **Renaissance Economic Development Corporation**<br>renaissance-ny.org | **Pursuit**<br>https://pursuitlending.com/ |
| **TruFund Financial Services**<br>https://www.trufund.org/ | **O lè rí àkójọ àwọn CDFI mìíràn ní Ìpinlẹ̀ New York nipa ṣíṣàbẹ̀wò sí**<br>https://www.nyscdfi.org/nyscdfis |